IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AYE TENI GBOGBO LA
No. 750. WEDNESDAY, JULY 22. 1964 (2D)

## Ọlọpa Kan Ku Si Ile Iwẹ

IKẸJA: Jinijini dabo gbogbo awọn Ọlọpa ati ẹbi Ọlọpa nigbati nwọn mura gdigidi lati le gba ẹmi Ọga ninu Ọlọpa kan ẹni Ogoji ọdun la eyiti o di pa nṣe ni Ọlọpa na ku si ile iwẹ.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe Ọga ninu Ọlọpa na Ọgbẹni Robert Ọkafor pe Ọkunrin na yio ṣe aisan kankan ti o fi di pe o lọ si ile iwẹ lati lọ wẹ.

Oniwe irohin wa tun sọ pe nigbati on tun sẹ iwadi lẹnu awọn ẹni Ọlọpa ni pe nwọn sọ pe ko si nkankan to ṣẹ Ọlọpa na rara titi de ibi Ọjọ iku rẹ.

Awọn Ọlọpa ẹgbẹ rẹ tun fi ye oniwe irohin wa pe awọn kan ngbọ pe Ọlọpa na ntara iku eyiti awọn si fi ṣi ilẹkun ile na pẹlu ipa ati pe oku okunrin na ni awọn Ọlọpa ba ni ile iwe.

Irohin tun fi ye wa pe Ọgbẹni Okafor ti wa ninu iṣe Ọlọpa fun o indi Ogun Ọdun ati pe tẹsan awọn Ọlọpa ni ibado Ọkọ Ofurufu ni Ọlọpa na ti nṣe Iṣẹ Okun rin na si ni iyawo kan ati Ọmọ mẹsan silẹ si aiye lọ

# Dokita Okpara Sọ Pe AJUMỌṢEPỌ N. C. N.C. ATI A G TI F'ẸṢẸ MULẸ

BENIN: Ninu ipade ti awọn igbimọ apapọ ẹgbẹ Alakukọ ṣe ni ilu Benin eyiti o jẹ ibi ijoko Ijọba ti Agbedemeji ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nibi ti awọn igbimọ ẹgbẹ na ti panupọ sibi kan p. eto nipa ajumọṣe ẹgb: Alakukọ ati ẹgbẹ Ọlọpẹ ti fi ẹṣẹ mulẹ ṣiri ṣiri

Ninu ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ ni ipari ipade igbimọ na ni ọjọ Aje ti ṣe ogun oṣu yi ni igbimọ ẹgbẹ na eyiti Dokita Michael Okpara Olori ẹgbẹ Alakukọ ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ti ṣe alaga igbimọ na ni awọn igbimọ na ti pinnu pe fun ajumọṣepọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre lo le mu eto alafia ati Ijọba rere fẹṣẹ mulẹ ni orilẹ-ede Naijiria.

Igbimọ Alakuko na tun sọ pe fun ilọsiwaju ati alafia ilẹ Naijiria yio dara pupọ ki ẹgbẹ Alakukọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Northern United Front (N U F papọ laseko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba Naijiria eyiti idibo rẹ yio waiye ni ipari ọdun yi,

Igbimọ ẹgbẹ Alakukọ tun sọ ninu ipari ipade wọn na pe gẹgẹbi eto ọrọ oṣelu ṣe nlọ si ni ilẹ Naijiria ba-



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹr

yi. awọn igbimọ na ni lati jẹ ọmọ ẹgbẹ nwọn to ba lo di si ofin ẹgbẹ na ni iya lati le fi han pe ohun to ṣe ko dara.

Ọgbẹni Mbanilike Amechi ti o jẹ akọwe eto irohin fun ẹgbẹ Alakukọ fi ye oniwe irohin wa nibi ipade na pe awọn igbimọ ti awọn ẹgbẹ won yan lati ṣe wadi Oloye T. O. S. Benson Alakoso to irohin fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria lori akitiyan re ninu ẹgbẹ alakukọ kon. bẹrẹ ipade na bayi ti Oloye Benson yio fi pada de lati irin ajo re si Cairo.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe wakati mọkanla ni awọn igbimọ ẹgb: na fi ṣe ipade na eyiti awọn to jẹ Olori ninu ẹgbẹ na si wa ninu awọn olori ẹgbẹ na to wa sibi ipade na ni Oloye Festus Okotie - Eboh, Alaeto isuna fun Ijọba apapọ Naijiria Ọgbẹni R. A Njoku Alakoso eto irin ajo fun apapọ Ijọba.

„IHAMỌ"



AMINU KANO
Olori Ẹgbẹ N. U F



Dọkita M. I. OKPARA
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

Ọgbẹni Amechi tun sọ pe awọn igbimọ ẹgbẹ na tun ti ṣe ikilọ fun Oloye Benson pe ki o ma ṣe ba awọn oniwe irohin ṣe ipade kankan lori ẹgbẹ tabi rogbodiyan to wa larin on pẹlu awọn ọmọ egbẹ na ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria titi awọn igbimọ yio fi ṣe iwadi akitiyan Oloye Bẹnson na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe awọn igbimọ egbẹ Alakukọ na si ti sọ pe Oloye Benson ni lati fi ara han niwaju awọn Oluwadi na lẹsẹ ẹsẹ to ba ti pada de lati Cairo ati pe awọn igbimọ na yio ṣe iwadi lori akitiyan Oloye Benson ninu ẹgbẹ Alakukọ.

Ọgbẹni Amechi tun fi ye oniwe irohin wa pe awọn igbimọ ẹgbẹ Alakuko bu ẹnu ẹtẹ lu Alakoso Ijọba ọlọla Alhaji Abubakar fun ikuna rẹ lori eto ikaniyan ile Naijiria ati pe nwọn ko ti abajade ẹnia kika na ki nwọn to fi ma ṣe eto Ijoko idibo fun apapọ ilẹ Naijiria

Ọgbẹni Amechi sọ pe

WO OJU EWE KẸFA

# IWE SI OLOTU

## Eleyi Nfẹ Itọju Ijọba

Olotu jọwọ ma ṣalai fun mi ni aye die ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati kesi Ijọba ibilẹ ilu Ijẹbu Ode ati agbegbe rẹ lati ṣe abojuto ọnọ ilu Ore -Ako eleyi fi jẹ iyalẹni lati ri pe lati bi nkan bi oṣu mẹjọ awọn Ijẹba ibilẹ ilu Ijẹbu-Ode to nṣe itọju ọna na kosi ṣe nkankan nipa ọna na bayi ati pe ako tuọ ibiti nwọn nna owo Ori wi ti ansa ni ilu Ake- Ako si ọna kan ṣoṣo to jẹ Pe Ijọba ibilẹ ilu ijẹbuOkenba wa jẹ amojuto rẹ ni ọjọ si ti da koto si bayi inu mi yio dun pap iwa ọmọ ilu ni ti anbẹ ni ilu E o yio dupẹ lọpọlọpọ bi ẹ ba le b wa tete ṣe atunṣe ọna na bayi.

A osi ma ni ireti nyin bayi o nitori ajafara lewu pupọ

Mo dupẹ pupọ Olotu ajinde ara yin si jẹ fun nyin ati alabaṣiṣẹ pọ nyin

Emi ni
Amusa Tiamiyu

EKO

mina parapọ ba je tabi ki o parẹ tabi ki o faramọ mọ ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) Enikẹni to ba daba pe ki awọn Ọmọ ilu Igbomina fara mọ ẹgbẹ N, P, C, Iparun ẹgbẹ Igbomoaa ni ti o yi ki a le bayi ati ẹyẹ fun ẹgbe na nitori o jẹ ẹgbẹ gbogbo Ọmọ Igbomina ati pe ki o le lo kiki ni ọjọ iwaju ati ni ẹhin Ọla, Nitori eyi ẹnyin Ọmọ ilu Igbomina ẹjẹ ki a ronu wa ki a fi imọ ṣọkan Mo dupẹ pupọ Olotu ajinde yio ma jẹ o.

Emi ni
Yesufu Owolabi

ISẸYIN

## Idahun Ibere Ọgbeni Olorun-logbọn

Olotu mi owọn inu ni yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ lati dahun ibere ẹrẹ mi ọgbeni Olorunlogbọn eyi ti ibere rẹ lo bayi pe: Nje eni to nbo lati ode lo yẹ ki o ko ki ara ile? tabi eni to wa ni ile bo yẹ ki o kọ bi eni to nbọ lati ode?

Ni okan temi o eni to wa ninu ile lo si ye ki o kọ bi eni to nbọ lati ode pe ko abo o Idi eyi ni pe nse ol o ni ichun ori ibi ibi kan bọ emi ko si mọ ohun to le fa to fi je pe eni to nbo lati ode ni yio ko ki e ti o wa ninu ile.

Ore mi ogbeni ọlorun logbọn mo fẹ ki ẹ mọ daju pe ẹni to mbọ lati ode pe ko a bọ O. Mo dupẹ pupọ o olotu ọkọ ọba ko ni ṣa ojin lẹẹ o atọm.

Emi ni
Saidu Akanbi
Oko—Oko Ilorin

## Idahun Si Ibere M. A. Odekunle

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti nkọ ni lede ti o njade lojojumọ lati le fesi si ọrọ ti Ọgbeni M. A, Odekunle sọ sinu iwe nyin oleyinmomọ ti o jade ni ọjọ keje oṣu keje Odun yi pe, Nje o ye ki egbe Igbomina parapọ parẹ bi? Ni temi o, emi ko faramọ pe ki ẹgbẹ na parẹ bi ko ṣe pe ki ajọ wa ni irẹpọ lati fi imọ wa sọkan lati le jẹ ki ilọsiwaju wa fun ilu wa Igbomina. Ẹniti o ba jẹ Ọmọ ilu Igbomina gidigidi ti ki iẹ ara ti ko si ni fi Ọmọ osi iwe ile Baba rẹ wa gbọdọ faramọ wi e ki ẹgbẹ Ọmọ Igbo.

## A Nfẹ Itan Ilu Igbaja Lati Ọwọ M. Atọlagbe

Olotu jọwọ gba mi ni aye ranpẹ lati rọ Ọgbeni Moliki Atọlagbe Igbaja ki o fun wa ni itan ilu wa Igbaja. Diẹ ninu awọn ọmọ ilu na lo le fi ọwọ sọ ya pe on mọ itan Ilu Igbaja,

Oun to mu mi sọ bẹ ni pe Ọgbẹni Atọlagbe ti sọ sinu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ kọkanla oṣu kẹta ọdun yi pe bi Olotu ba le fun on ni aye pe on yio gbinyanju lati sọ itan ilu Igbaja sinu iwe rẹ oloyinmọmọ fun awọn ọmọ ilu na gbọ.

Lati igba na Ọgbẹni Mọliki Atọlagbe ko si fun itan na awa ọmọ ilu na si ti nreti pe awa yio ri itan ilu na ka laipẹ.

Inu wa yio dun pupọ bi Ọgbẹni Opitan na ba le tete kọ itan ilu wa na simi iwe Irohin Imọle lati le jẹ ki awa ti a ko mọ itan na le ri i ka

Inu wa yio dun bi Olotu ba le tete gba Ọgbẹni mi Atọlagbe laye lati tete kọ itan na bayi

Emi ni,
K, B, Ọmọ Ẹgbẹ
Baiẹ ilu Igbaja

## AKIYESI

Fun ẹnyin to nkọ iwe si Olotu Iwe Irohin Imọlẹ ti ẹ ba nfẹ ki iwe nyin ma jade laseko mo bẹ nyin ki ẹ jẹ ki iwe nyin han ketekete lati le ki Olotu tabi awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ le mọ nkan ti ẹ kọ sinu iwe nyin. Ṣugbọn ti a ko ba le iwe rẹ jade na sẹ binu ati pe ohun ti o kọ si wa ni ko dara to bẹ Nitori eyi ti o ba le kọ ki o dara bẹ ki awọn ẹrẹ rẹ ki nwọn ba ẹ ko.

OLOTU

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!




PORAL

OLUṢỌGI EGBOGI "IKỌ"

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu on akan bi ọdun kan tabi ju ẹ lo awọn egbogi rọ irọbi fu le se Iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara. Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun Iko otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Ikọ iile, Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba ti ra Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iyato ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jeun daradara iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisirisi Ile gi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọjaita Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba
ATI NI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi Iwe Itufọ tabi Ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone : 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
IROHIN KO TO AFOJUBA
Oun wa wo lẹẹkan ṣo ko si ri iyato

# Ọkunrin Kan Sọ Pe Nwọn Ran On Lọ Jale

YABA:— Gbogbo enia to wa ni ile ẹjọ ni Yaba lo bu sẹ'rin nigbati Ọdaran kan Tunji Adeniyi fi ye adajọ ile ẹjọ kekere Ọgbẹni Francis ogunmuyiwa pe nwọn sọ fun on pe ti on ba kuna lati lọ jale pe nwọn yio pa on ni.

Tunji Adeniyi to tun fi ye ile ẹjọ pe on fi ni irin ẹsun olejija na eyi ti ile ẹjọ fi ẹsun ole jija pe o lo fi Taya mọto eyi ti Ọmọ rẹ jẹ pon-un mẹfa (£6) ti Ọgbẹni paul Afọlabi ni ọjọ kejila Oṣu kefa Ọdun yi.

Agbẹjọro fun ile ẹjọ na fi ye adajọ pe Ọgbẹni Afọlabi fi ara gbọgbẹ niun jamba mọto eyiti o fi mu mọto rẹ ti o ku si ẹba ọna Morris Street, Abule Ijẹsha, Yaba lati lọ ṣe itọju ara rẹ ni ile iwosan.

Agbẹjọro fun ile ẹjọ tun sọ pe ọdaran na si lọ sibi ti mọto na wa o si yọ taya rẹ kuro nibi ti o ti nyọ taya mọto na ni nwọn ba ra-gabu rẹ ti nwọn si mu u lo si tasan awọn Ọlọpa.

Ninu idajọ rẹ ọgbẹn francis ogunmuyiwa sọ pe odaran na si ti wa jẹ jọ niwaju on fun iru ẹsun ole jija yi oni sugbon on si da ọdaran na sile fun ẹsun ti nwọn kan fi adaran na pe ko fi ẹsẹ mulẹ dada ọgbẹni Francis ogunmuyiwa tun fi ye ile ẹjọ pe olorun nse iṣẹ rọ ati de on lo tun jẹ ki ọdaran na tun lọ jale niarau eyiti o tun fi wa si iwaju on. Adajọ ile ẹjọ na si ju Tunji Adeniyi si ẹwọn ọbun meji pẹlu iṣẹ ase kara.

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Maṣe fi ikanra inu ti yio bi ọ loni mu ọmọnikeji ẹ ki o si ko ara rẹ ni ija-eu pẹlu ọrọ isọkusọ.

PISCES (Feb 19 - March 20) Gbiyanju lati ṣe ibẹ-wo awọn enia rẹ tabi awọn ọrẹ rẹ loni, bogbo ohunti o ba nṣe lẹhin na rere ni yio ma yọri si laisi alatako.

ARIES (Mar 22 - April) Maṣe huwa ti olufẹ rẹ yio fi ma a jowu tabi ti ori olufẹ rẹ yio fi me a gbona loni nitoripe ifẹ ailegbe ni olufẹ ẹ ni si ọ

TAURUS (Abril 20 - May 20) Awọn ohun isoro kan wa loju ọna fun ọ loni ti yio mu inu bi ọ, lẹhin ibinu ailera ara yio si wa fun o ti ohunkohun yio fi sun ọ.

GEMINI (May 21 - June) Maṣe fi iṣẹ aṣeju ṣe ara re lẹṣẹ loni, gbogbo idawọ'e rẹ lẹhin na rere ni yio ma yọri si.

CANCER June 22 - July 22) O ni ifẹ lati ṣiṣẹ loni, ti gbogbo nkan yio fi ma a wu ọ lati ṣe, ṣugbọn maṣe kọ imọran ki o ma ba ki ika abamọ ọ enu gbẹhin.

LEO (July 23 - Aug 22) Ṣọra pẹlu ọrọ asọju lon ki o ma ba fi ẹnu ṣẹ, ki o si tẹ lọwọ awọn to feran rẹ si yio fi di ohun ti yio mu ibinu wa fun ọ ni igbẹhin.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ọjọ oni dara fun ọ ti o ba siṣẹ owo kan loni, iṣẹ ẹẹjẹre wa fun ọ, o gbọ iro-hin kan ti yio mu inu rẹ dun lalailo to ṣu loni

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Maṣe kọ ipade kan ti awọn ọrẹ rẹ yio pe ọ loni lati jọ lọ si ode kan gbogbo ohun ti o nfẹ ni ọwọ rẹ yio tẹ ki ilẹ to ṣu bi o ba ba wọn lo Awọn olufe rẹ ni ifẹ si ọ dada maṣe dalẹ ọrẹ.

SCORPIO Oct 24 - Nov 22) Agbara wa fun ọ lati ṣe iṣẹ re loni daada, inu awọn enia yio ma a dun si ọ ṣugbọn ṣe a pẹlu owo inakuna ki o ma ba ke abamọ pi ikẹhin nigbati owo ba tan lọwọ rẹ.

SAGITTARIUS (Nov 24 - Dec 21) Ṣọra lọpọlọpọ ki o mase ma a ba awọn ọga re jiyan lori iṣẹ ti inu ba nbi ọ tabi ọran ba ndun ọ lọkan fi ọrọ rẹ han awọn enia ki o si gba imọran ki lọsiwaju ati igbega o ba le wa fun o.

CAPRICORN (Dec 21 - Jan 19) Ọjọ aṣeiere wa fun ọ loni, gbogbo ẹkẹṣẹ rẹ sẹ si ndi pe ẹlẹ lọ. o si ṣe alabapade awọn kan ti yio fun ọ ni imọran rere ti yio ṣe ọ ni anfani ti o ba le lọ wọn.

MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos.

**I. C. M. Tọniki** (100 Tablet



Gbiyanju lati ma lo I. C. M. TỌNIKI nigbagbogbo I, C, M, TỌNIKI o wa fun Ọkunrin, Obinrin ati Al bo yun pẹlu. I. C. M. Tọniki o dara fun aini ẹjẹ to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun ẹjẹ ṣe daradara. Bere fun eyọ igo kan, tabi dọsini. ẹdidi Apoti (50 dozes) wa pẹlu. Ilera ni ogun ọrọ o Bere lọwọ Elegbogi oyinbo ti o wa ni adugbo rẹ fun I. C. M. TỌNIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si ọdọ:—
MOSỌBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Street

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ILE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi ara ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara won iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ tabi fun awọn ailera gbogbo iyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de aderin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMI-REN" ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata oju re a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i dan pada Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu igoọaba dun ati alafi diro de ẹ. Iyẹn daju Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AYE TENI GBOGBO LAWA

No. 750, WEDNESDAY JULY 22, 1964 (2D


## Dokita kan Wewon Odun Meje Fun Esun Ti e O Şeyun

AKURE:— Ni ojo Aja fi işe Ogunjo oşu yi ni adajo ile ejo ganran ti Akure Ogbeni Beckly ju Okunrin Odaran kan eni ogbon odun si ewon odun meje fun un pe ko ba Oluko Obinrin kan Mrs Massey Adeleke şe oyun eyiti o fa iku Oluko na wa, Okunrin Odaran na Ranji Ogulu ti wa ni ile iwosan ti Wesly Guilde Hospital, Ileşha tele.

Adajo ile ejo na Ogbeni Beckley si ey Odaran na Ogulu jebi esun pe o şe oyun oşu merin eyiti o fa iku o iyan Massey Adelasiwo.

Ninu oro agbejoro fun ile ejo na Ogbeni Olaolu Adeniran fi ye ile ejo ni ninu oşu kefa odun 1962 pe odaran na Ranji Ogulu gba omo binrin nasi ilerae gegebi eni to nşe itoju re ati pe odaran na si i fun omo binrin na ni ogun ta le fi şe oyun inu nigbati odaran na mo pe oyun na ko şe şe rara ti fi di pe di iwosan lo le pope si ara omo obinrin na lara lo na tile gbe lo si ile iwosan lati ile dara na ma ti o ti nfun ni ogun di Effo Alaye ni egbe Ekiti agbejoro na so pe ko pe odaran na gbe omo binrin na ile iwosan lo ba ku.

Ninu ojo awijare odaran na o fi ye ile ejo pe okunrin kan ti nje Ajiboyi to wa ni ilu oyi bo bayi lo mu omo binrin wa si odo fun to ju.

# AWON OKUNRIN ATI OBINRIN ONIŞOWO OJA AWOLOWO ŞE IPADE

MUSHIN:— IROHIN o to afojuba ni Ojo Aiku ti işe ojo keje Oşu yi nigbati awon Okunrin ati Obinrin Onişowo ti oja Awolowo se ipade won ni ile itura ti Alhaji Seriki ni deede agogo meji Osan ki ipade na to bere Opolopo awon Omo egbe Onişowo lo si ti pese sibi ipade pa ki gbogbo won to de.

Ninu oro ti awon Omo egbe na so nibi ipade won na ni oro ija kan to şele larin iyalode egbe Onişowo ti oja Awolowo Mushin Iya afin Akanke Lawal eyi ti o jade ninu iwe irohin ni ojo keje Oşu yi eyiti Iya-afin O Ajose fi so pe ki işe Iya afin Akanke Lawal ni Iya lode oja na.



Oloye AWOLOWO

Irohin fi ye wa lati odo akowe egbe Onişowo na pe ija to wa larin awon Obinrin mejeji na lo si mu ki Iya afin Ajose fi so pe Iya afin Akanke ki işe Iyalode oja Awolowo ati pe Iya afin Ajose papa si je Iya egbe awon Onişowo awon Elewa ati oni Rice ni işe Opolopo awon enia jankanjankan lo si wa sibi ipade ojo na ninu won ni Alhaji Shittu Momo ti o je alaga egbe na Oloye T. I. Sango tadi Bale oja, Omo Oba M. B. A. Olojo akowe, Iya afin Folaran ni ni Aduke Iya Egbe Iya afin J Oladeinde alaga Obinrin Iya afin Ayisatu Buraimo Balogun, Iya afin Ebun Fakoya otun Iyalode.

Iya afin M. Lawal Ekeri oja, Alhaja S.Alarape Adekayaoja Alakoso oja A. G. Mar hunkeji Iyalaje, Alhaja Sarat Kashimara Iyaloja Iya afin Shifawu Oladunni Apase Oja Iya-afin Esther Iyabo, Adebisi Oladosu i balej akowe ati Ogbeni S. Agbabiaka Are oja.

Ki awon egbe Onişowo oja na to mu ipade won lo si opin nwon si dupe gidigidi fun akiti yan awon Omo egbe na ni oja na ati pe nwon si ro gbogbo awon Omo egbe na lati ni eru işokan Ni ipari awon Omo egbe si ni awon ni igbekele ninu olori egbe Afenifere Oloye Awolowo ati Adele re Alhaji D. S. Adegbenro Awon Omo egbe na si tun si pe gbon-gbon ni awon duro lehin egbe Afenifere.

Awon omo egbe on şowo na lokunrin ati l'obinrin to wa ni oja Awolowo Mushin si so pe Iya afin Akanke Lawal ni awon mo gege bi Iyalode oja Awolowo

## Ajumoşepo NCNC Ati AG Ti F'eşe Mule

LATI OJU EWE KINI

eleyi fi han gbangba pe iru iwa bayi ti fi han iru nkan to le şele lase idibo si ile igbimo asofin ti apapo Ijoba.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe awon omo egbe Alakuko tun so pe awon ko ni fi ya lori eto enia ki ka sile titi awon yio ri oti to abyori eto enia kika ile Naijiria ki nwon tun le esi na jade.

Awon igbimo egbe N C N C na tun so ninu ipade won pe awon si ogbero lati gba ninu awon omo egbe won ti nwon ti yo kuro ninu egbe na pada ati awon omo egbe na ti nwon duro gedegbe ni ile igbimo asofin ipinle Ila orun Najiria.

Ninu oro ti Olori egbe Alakuko ati Alakoso Ijoba ipinle Ila Orun Naijiria fi nye awon oniwe irohin nigbati o pada de si ilu Enugu lati Benin ni ojo Aje ti şe Ogunjo oşu yi, Dokita Okpara so pe gbogbo ijo to wa ni ipinle Arie ni awon omo egbe ti mo enia sile eyiti Ijoko won si je merin lelodosan (174) seats.

Nigba awon Oniwe irohin nbere lowo Okpara nipa rogbodiya to be sile ni Tiv ni ipinle Ariwa Najira Dokita Okpara so pe on ti kesi Ijoba apapo ki nwon tete da si oro na.

Dokita Okpara so pe gba gbogbo ni ja si nşe e ni ilu na ati pe ohun to yo ki Ijoba apapo se ni ki nwo şe iwadi ohun to nfa rogbo diyan sile ipinle na.

LATI OJU EWE KARUN

Oloye Awolowo tun fi ye ile ejo pe on pelu elegbe on ati olo Akintola lo ba Alakuko ijoba apapo olola Alhaji Abubakar ori eto Ijoba ajumoşepo fun gbogbo ile Najiria.

Oloye Awolowo tun fi han ile ejo nipa awon oro ti on pelu Alhaji Abubakar jijoso lori nkan to nlo lo ni ile Najiria.

Oloye Awolowo tun so pe on si tun fi sun apapo Ijoba Alhaji Abubakar wo ojo kewa oşu kejo odun 1962 ati pe on pelu Alhaji Abubakar jijo pinnu sibi eyiti nwon kuna lati gbe jade.

Şiwaju si Oloye Awolowo so pe on ko ... si Olola Abubakar ati lati ... oro jomitoro ... won ni ojo kerinlelogun Oşu kesan Odun 1962 nigbati Oloye Awolowo wa labe ofin pajawiri eyiti o fi wa ninu ihamo.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 22/7/64.